**Owe**

KITA-KITA KOMỌ TI ARISIKI, KI A ṢIṢE BI ERU KODA NKAN

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

ENIA BI IYA KOSI TANI JẸ Ṣ'ỌMỌ ỌLỌMỌ LORE.

VOL. XIII No 706 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 16, – SEPTEMBER 22, 1961. KOBỌ MEJI (2D)

# OGUN BE SILE NILU KATANGA, ALAKOSO TSHOMBE F'ESE FE E!

Leopoldville– Irohin kan wa lati ilu Kongo wipe ogun ti bẹ silẹ nilu Katanga Alakoso Tshombe si ti f'ẹsẹ fẹẹ lo wa ibi sapamọ si. A gbọ pe ogun na bẹrẹ ni dede agogo mẹrin owurọ, nwon si fi ọpọlopo wakati ja ogun na, owo tẹ meji ninu awon Alaṣẹ ijoba Tshombe nilu Katanga.

Awon ọmo ogun Katanga bẹrẹ ija ni ile Ifiweranṣẹ (Post Office) ti ilu Elizabethville ni oru'gänjọ ṣugbọn ọmọ ogun ti Igbimọ Agbaiye le wọn pada pẹlu ọpọlọpọ emi ti o ṣofo. O to adọjọ enia ti o ku ninu ọmo ogun Katanga, awon ọmọ ogun ti Igbimọ Agbaiye le ni ọgbọn enia ni. Nwọn dana si ile itẹju ohun ija ogun Katanga nilu Elizabethville, ija si nlọ bi rẹrẹ.

Moise Shombe ti o ti salọ ti tun pada wa sile pẹlu ọpọlọpọ awọn Ṣọja ti o fi ṣe aabo ara rẹ ṣugbọn awọn Olori ogun Igbimọ Agbaiye sọ wipe awọn yio kan lara.

A gbọ pe ọdọ Oyinbo Aṣoju ilẹ Gẹsi ni Tshombe kọkọ sa si fun aabo, ṣugbon ara rẹ ko balẹ sibẹ ki o to tun sa kuro nibẹ. Kole duro nibikan ki o to tun pada sile rẹ, nwọn sọ wipe Igbimọ Agbaiye ti gba ilu Katanga, ọrọ ti yiya sọtọ ko tunle waiye mo.

Ilu Oyinbo Gesi ko fẹ fi ara mọ iṣẹ ti Igbimọ Agbaiye nse ni Kongo nisisiyi, ṣugbon Ijoba ile India ati awon miran gba fun Igbimọ.

Bi o ba ti nlọ si, ọo ma gbọ siwaju.

## Olola Nla Duke Ti Devonshire De Silu Eko



Gegebi a ti ro irohin re si apakan iwe irohin wa ti ọsẹ tokoja, Ọlọla nla Duke ti Devonshire na ti de silu Eko ni owurọ ọjọ Jimọ ana, o si ba awọn Oniwe irohin se ipade po ni agogo mokanla owurọ ana ninu ile onje ti awọn npe ni Federal Palace Hotel l'ọna okun Alosin.

**NOW OPEN**

**Messrs J. H. DOHERTY LTD.**

**Department And SUPERMARKET**

**"BANUSO STORE"**

80/88 BROAD STREET, LAGOS

(OPPOSITE THE CENTRAL BANK AND NEW B. O. A. C. OFFICES)

# OFIN KO MO ENI-OWO

LONDON — Agbalagba oyinbo ajiko didan ninu ... ti o ... d'agba d... emi ọdun mọkan-din-lọgọrun ... o'ọ ori rẹ ti nwọn npe ni Lord Russell, ... Kotu kekere ṣa si ẹwọn oṣu meji nigbati o kọ lati f... ara rẹ dogo lati ma a ṣe jẹjẹ tabi ... so agbeje ... m d...

L... n... ti ... ọdọ Oniṣegun (Doctor) ... adajọ ... Lord Russll, adajọ din ẹwọn rẹ ku si ọjọ meje pere.

Iyawo ... ti o je ... ọgọta ọdun ni nwọn ... ẹwọn ... meje ... ni Kotu adajọ kekere ti Bow Street, nilu Oyinbo.

A gbọ wipe ... ti o gbe ... Kotu niti ikede ti o nse wipe ... ọn enia to tako ... iṣẹ ogun şişe.

Nigbati Kotu bi lere bi o ba fẹ ki nwọn sọ ... mọ ... o fesi ... hun pẹlu ... ti o la ... wipe "Agbedọ, emi ko fẹ".

# ONISE OKO OFURUFU TI O JE OSERE BOLU



OGEENI Gordon West, ... ilu Oyinbo Gesi ... oko Ofurufu, ni o nse alafehinti (Goal-keeper) egbe agba bọlu ti nwọn npe ni Blackpool o si je ... ọdun meta-din-logun.

# Imoran Fun Gbogbo Omo Ile Igbomina

Lati Ọwọ A.R.A Orilonishe

Olotu,

Gbami laiye lati ba awọn ọmọ ilẹ Igbomina sọ-rọ. A'ọkọ oro mi si yin Ẹnyin ọmọ ẹgbẹ Olomi, (N.P.C.) Omu-Aran. O njẹ iyalẹnu fun ... wipe "A nje Ekuru kotan lọwọ ẹtun ngbọn ọwọ imiran si," nie iru iwa alai lero ati wipe Onipọti... ato- niyin. Bole bai k'oba'e, ni Ẹ duro fun ni ilẹ Igbomina. Oluwa Ọba kọ si ni bẹjẹ. Gẹgẹbi iru nkan ti awọn ọmọ Elomi (N.P.C.) Omu-aran dawo ni oṣu August 27th 1961, won lọ ko okuta dani fun Hon. J.G. Ẹkunrin, won bere si okuta si mọ.o rẹ ... ọn f... pa. Ẹyin ọmọ Ẹgbẹ Olomi (N.P.C.)

Ẹ ko lero wipe bi ẹ ba pa Ẹkunrin ogun nla lẹfẹ d... s'lẹ larin Oke-Ọdd... ati ilẹ Igbomina. Ṣugbọn Oluwa ọba ti dajọ fun Ẹda yin m... da fun yin. Bi o ba ti dara bẹe. Owe awọn Baba wa kan sọ bayi "wi" "A ngba ọmọ ẹdẹ lọwọ iku, o ni ako jẹ ki on lọsi ekitan lọjẹ". Awọn ọmọ ẹgbẹ Igbomina nja fun wipe kole rọ gb gbo wa lọrun, ẹnyin ọmọ ẹru ti nwọn gbe wa ile Igbomina nso wipe Oko-eru lo fe kusi. Sugbọn ẹ ura mi ni wipe Oluwa kotete dayin pada.

Ẹnyin ọmọ Ẹgbe Olomi (N.P.C) o ma ṣe, opọọ. Ẹku-a'ri kan-ṣekan. mofe sọ fun yin wipe igbehin l'o ndu oloku adasi. Akọkọ eyin ọmọ Omu-Aran Odi ore melo ti awọn N.A. Ilorin to wa ni agbara ṣe fun yin? Ekeji moti s.rọ kan ṣiwaju ọrọ na lo nọe si wọn lara, mo ri ko si ọmọ gidi larin yin. nwọn wa wo yin ni ile Igbomina ni, mo fe bere awọn ibere yi lọwọ eyin ọmọ egbe N.P.C. Olomi ile Igbomina.

(Wo yoku loju ewe karun)

# ITAN AJAPA ATI EIYE

Ni ilu kan iyan mu pupo ti o fi je pe Ọba ilu ko ri onje'e afi Ẹiye Aparo nikan ni onyo o si nyo ikun. Ni ọjọ kan ajapa lo ba eiye oni ko fi ibiti o ti nri onje han on Ẹiye ani iati fo ori omi koja ki a to de ibe Ijapa ni ko buru oni ki o so iye mo apa on, ki o si gbe on pọn.

(Wo yoku loju ewe kefa)

## Owo Ipese Sile Fun Ojo Ola

EKO— Alaṣẹ iṣẹ Ijọba Apẹṣe Ọgbẹni J. M. Johnson ni o ṣe ikede lori ẹrọ asọrọ-magbesi nilu Eko ni ọjọ ọsẹ (Sunday) wipe Ijọba Apapọṣe yio da Ipese-silẹ owo fun ọjọ ola silẹ fun awọn oṣiṣẹ ilẹ Nigeria lati ọjọ kini osu October, ọdunni, ti iṣe ọjọ ajọyọ kini ti ominira.

Alaṣe iṣẹ Ijọba se alaye siwaju wipe ohun ti o mu Ijọba fẹ ṣe bẹ ni wipe Ipese-silẹ ko to fun awon oṣiṣẹ ilẹ Nigeria, fun ọjọ iwaju nigbati enia ba fi iṣẹ silẹ tabi ti o di agba ti ko tun le ṣe iṣẹ mọ.



Alaṣẹ iṣẹ Ọgbẹni Johnson sọ wipe Ipese-silẹ ti Ijọba fẹ da silẹ yi ni ọpọlọpọ anfani ninu fun awọn oṣiṣẹ nitoripe sile kan lori owo ọgbun kan ti oṣiṣẹ ba ngba ni yio ma da pamọ, ti agbani siṣẹ yio fi sile kan kun u, lẹhinna ni nwọn yio tun ṣiro ele kun un oṣiṣẹ na.

Eyi jẹ ifiyabalẹ fun awọn oṣiṣẹ nigbati ọjọ ba di alẹ.

Ao ṣe alaye rẹ fun yin lẹkunrẹrẹ nigbamiran.

## ODUN ORUNMILA

(Lati Ọwọ Ọgbẹni Gbadebo Dosumu)
Olulana, Ijo Ti Afrika) Ọrunmila (W. A.).
Eriwo Ya (Mẹta) Ayagbo, Ayatọ (Meta).

(O tere ninu iwe wa ose tokoja)

LONI, Ọrunmila ti wa ni Aiye ati Ilu Aṣotitọ pẹlu awọn nwọnni ti iṣẹ tabi iṣe wọn ti gbe wọn de Ilu Asotito Nibo ni Aiye yi tabi Ilu na wa? Aiy na tabi Ilu na ni AIYE-A-RE-IBỌ, Ilu ni ti awọn ti iṣẹ nwọn L'Aiye-nbi ti pari ti IWA ati Iṣẹ Nwọn gbe de Ilu na nipa IṢẸ RERE awọn bẹ Ọrunmila li Ẹnti o Njọba nibẹ lori awọn ẹni Rere ni-o pẹ,o ya, iwọ ki yio ha de ibẹ bi? Iwọ ki yio ha gbe Ilu na bi? Iṣẹ ọwọ rẹ ni yio gbe ọ de ibẹ. Ki Ẹlẹda jẹki ori inu wa o mu wa ṣe iṣẹ ti yio mu wa yẹ fun Ilu Mimọ, Ilu Ẹleye, Ilu Ọlọla, Ilu-alai-labawọn na.

HUN-HUN, Hun. Iwọ yio kọkọ se iṣẹ ti yio mu ọ kuro ni ilu ṣikaṣika, ti yio mu ọ de Ilu Aṣododo. Ni bo ni Ilu Aṣododo ati Ilu Ṣikaṣika wa? L'Aiye-nbi tabi L'Aiye ti a wa yi ni. Aiye yi ni ilu Aṣododo ati ti Ṣikaṣika. Awọn eni ti o wa ni Ilu Aṣododo ni awọn nwọnni, ti Nwọn mọ, ti nwọn nṣe Iṣe ANU, Rere tia wọn si ndu nlati ma se Otitọ ati Ododo ninu igbesi Aiye ati i-se wọn ni ojojumọ.

Ṣikaṣika ni awọn bi-aba-ki-o-pa, bi-oko-ba-ki-o-bu-lẹse; awọn ti o nse ẹni-ẹlẹni-ni-sika-sika-alai-lanu ika, alagbapa ati bẹ-ẹ-bẹ. Njẹ, mo bi ọ lere, iwọ wa ninu awọn ilu mejeji wọnyi? Ronu, ba oriinu rẹ jiro-rẹ, nitoripe bi iwọ ba se Rere, iwọ yio ka rere, bi iwo ba se ise ibi, ibi ni iwo yio ka. Ro inu re wo ni ohun ti iwo yio se ni odun titun yi ________________ Ẹketa.

(Iyoku di ose tio mbo)

## Ajodun Ominira Ni Ipinle Iwo-Orun

IBADAN - Ninu ikede ijọba ti o jade nilu Ibadan ninu ọsẹ to kọja so wipe meta ni nwon a fi se ajoyo na.

Akoko bere ajoyo ominira yio bere ni ojo Jimo (Friday) ojo kokan-din-ogbon osu September yi, pelu idupe ati adura pataka ninu gbogbo Mosalasi ipinlẹ Iwọ-orun.

Ni ọjọ keji, ọjọ Satide ni awọn ọmọ-ogun yio to si gbangba-tẹju ọdan ti nwon ngba bọlu ti nwọn nṣe ni Liberty Stadium nilu Ibadan, ibẹ ni Gomina Ipinlẹ Iwọ-orun Ọlọla Adesoji Aderemi, Ala yeluwa Ọba Ọni Ile-Ifẹ yio ti bẹ awọn ọmọ-ogun wo.

Ni ojo ọsẹ (Sunday) ti ise ojo ajodun gan-an ọjọ kini osu October, gbo ile isin igbagbo Churches) ni yio gbadura ati idupẹ lọdọ Ọlọrun yika gbogbo ipinlẹ Iwọ-Orun.

Nilu Ibadan, ninu ile isin n'la ti St. James ni Olori Alufa, Ẹniọwọ S.O. Odutọla yio ti ṣe akanṣe iwasu pataki fun ajodun na. Ni alẹ ojo kanna ni Olori Ijoba Oloye S.L. Akintola yio farahan ninu ẹro Alaworan lati ki gbogbo enia ipinlẹ Iwo-orun fun ajoyo ajodun Ominira na. Nwon yio si ṣe ikede oro re ninu ero asoro-magbẹsi ti ipinle na fun fun enikeni gbo.

Ni ojo Monday ni lotu Ijoba yio lo gba ikinni awon omo ilewe ni Liberty Stadium, yio si ka oro iyanju ominira niba fun gbogbo enia. Ni alẹ ojo na ni nwon yio se apejẹ nla kan ninu Gbongan nla ti Iwo-orun, ilu Ibadan ninu eyiti nwon fi iwe pe le-legbẹrun enia pataki-patak

## ABESE-KUN-BI-OJO



Ọgbẹni John Caldwell ti ilu Belfast nilu Oyinbo Gesi ni o bori ninu iporogan ere ẹsẹ ti on pelu Ọgbẹni Alphonse Halimi ti ilu Faranse ṣe nilu Oyinbo laipe yi.

Ọgbẹni Caldwell ni o nfi ẹnu kan ohun ami iṣẹgun ti o gba nigbati o bori ninu ija na.

# Asare Bi Ategun



OGEENI Bobby Brightwell ti a nwo ninu aworan yi ni o ba won sare ije ti ilu Oyinbo Geesi pelu Faranse jumo sa po ni ilu 'nla London laipe yi. Bobby je okan ninu awon egbe elere idaraya ti awon J. D. Wrighton, B. Jackson ati H. M. Yardley wa.

Awon elere idaraya na ngbaradi nisisiyi sile fun ati lo silu Rome pelu ireti lati gba ohun ami iyin golu bo wale.


## OKU'JA WOLU

NIBGA TI OJA KO BA TA, TI ENITI ONRA OJA KOTA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI SE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONISOWO LE SE TI OJA RE YIO FI MA TA BI ISU AKARA GBIGBONA.

E Polowo 0ja Nyin Sinu Iwe Irohin ELETI-OFE


# Nwon fi As'a olopa ilu Saro ta Oga olopa lore



Olopa obinrin, Conneh ti ilu Saro ni a nwo ninu aworan yi ti o nfi asia olopa ilu Saro ta Oga olopa obinrin lore, Winified Barker, ti o je oga gbogbo olopa obinrin ti o wa nile ise awon olopa ilu Oyinbo.

Awon olopa obinrin mokanla ni o ti wa 'se ayewo orisirisi bi nwon ti nsise nile ise awon olopa ilu Oyinbo.

# OKE MEWA ENIA SA FI ILU SILE

AMERIKA — O fere le ni oke 'mewa enia ti o sa fi ilu Louisiana ati Texas sile nigbati oji lile su dede ti o mbo ni ebute Ila-orun ile Amerika.

Ni ale ojo Satide ni Alakoso Ilie Amerika fi ero isoro ba Gomina Texas ati Louisiana soro lori iranlowo fun awon to sa kuro ati awon ti idamu na kan.

Eniti o fi oju ri oji lile nigbati o dide ni dede agogo mejo ale ojo Satide so wipe o tobi depo ti on oiti ri iru re ri, omi ti o kun ya wolu ni gbogbo oju Opopo ona ga to ese mewa ninu eyit o ja ninu odun 1957, ti o pa ogogorun enia danu


E ma ka iwe irohin Eleti-Ofe. 0 kun fun irohin Aladun.

NO. 166

## ADVERTISEMENT

The Ministry of Communications announces that a special set of postage stamps will be issued on the 1st of October, 1961, to commemorate the First Anniversary of Independence.

2. The issue will comprise of five values having the following designs:-

2d. — Armorial bearings of the Federation.

4d. — Map Showing the natural resources of Nigeria.

6d. — Nigerian Eagle

1/3. — Birds in flight.

2/6 — Nigerians with the Nigerian Flag.

3. The Ministary will make available First Day Covers, wh'ch should prove to be attractive souven'rs of the occasion, at a cost of 5/- each.

4. Applications for these First Day Covers from persons resident in Nigeria should be forwarded to the Head Postmaster General Post Office, Lagos. Each application should be accompanied by a remittance of 5/- for each Cover ordered, together with a typed addressed label not larger than 3" x 2" suitable for gumming on to the First Day Cover. The envelope containing the application should be endorsed "First Day Cover" at the top left hand corner.

5. Applications for First Day Covers must reach the Head Postmaster not later than 25th of September, 1951.

**Ibanuje Tabi Ironu re de Opin Ayo de!**

BERE EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:

**"CORSIVERA"**

Ojulowo ati Ajẹbidan Atam matase Egbogi ti ase ni pataki fun:-

"ARỌN KINIṢA TABI ARỌN LATỌNLATỌN" MEJI RẸ KOSI.

Bere lọdọ awọn :-

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria
Phone: 22878 (Oja ita Faji)

## Imoran Fun Omo Ile Igbomina

( O bẹrẹ loju ewe keji )

Akọko ni wipe A gbọ wipe ijọba wa lọwọ yin. Ki wa ni anfani ti awon Ijọba ile Hausa ṣe f u n yin.

Nje Boba je wipe ekan ninu ọ m ọ egbe Igbomina Parapọ lose iru iwayi. Seria kini efe da fun ?

Nje Mr. Ọlanrewaju (Minister of State) t o j ẹ aṣoju Omu-aran ki o lọ si apa bomiran ni ilẹ Igbomina.

Odi ẹlẹ melo ti awọn ọmọ ẹgbẹ Igbomina parapọ (Action Group Alliance) lọ ko okuta dina fun Aṣoju ile ọdọ yin tabi ninu awọn aṣoju ilu yoku.

Ẹyin ọmọ Ẹgbẹ N.P.C. Olomi n j ẹ ẹle sọ Itan bi nwọn ṣe bi yin ni ile Igbomina koro l a r a yin Mo nfẹ esi awon ibere wonyi lati ẹ d o ẹyin o m ọ ẹgbẹ Olomi (N.P.C. iyẹn duro be. Oluwa kojẹ ki o tete ṣe yin o.

Ẹyin ọmọ Ẹgbẹ Olomi ilẹ Ileri ti ẹ wa n i n u aṣoju ilu mo fẹ mo lati wipe loto ni ijoba wa lowo yin. Ṣugbon igbati Mr J.G. Ekunrin mu report wa si odo yin, wipe awon omo egbe N.P.C. Omu-Aran lo dena de on, won si bere si le ni okuta, ki o wa ni to tiyin ki ẹ wa ṣe nibẹ? Ṣugbon o jẹ ẹ d u n okan mi lati so fun yin wipe ki iṣe ijoba to ni aluborika ni ijọba N.P.C Ṣugbon emi feti yeyin wipe Efe da Ile aiye ru ni ẹ ko fe lati tun ṣe. Ṣugbon Oluwa ko ni jeki o ti oro awa Ọmo Igbomina baje.

(Iyoku di ọsẹ to mbọ)

**KEKE ALUPUPU OLOGERE OLOJU-MEJI**



EWO odomobinrin ti o mu Keke Ologere Alupupu re d a n i pelu oju atupa nla nla meji ti imole re ko legbe bi nwon ba tan ni oru, o si le rin Adorin ibuso ni wakati kan.

## ITAN AJAPA ATI EIYE
(O bere loju ewe keji)

Eiye sigba be o se gegebi Ijapa ti wi, igbati won de ite eiye je, awon ba ti fiara je ti o si tun ko da ni igbati won nlo ekan bo ninu merin o ku eta ... ni on gbe meta y ku dele.

Ibiti o ti nso lowo ko tun bo o ku meji eiye ri ... di meji yoku dani dada, Ijapa nbinu ibiti o ti nbinu meji y ku bo omi Ijapa si ke to awon eso na. O ni ibiti won ba nlo ni awon yio jo d e k o pe ti Aja we die ni o si re.

(Iyoku di ose to mbo)


## J. A. Ajao Brothers

Head Office:- 10, Egerton Road,
P. M. Bag 2278, Lagos, Nigeria.
Phone—21941, 21521, & 21522

EXPORTS: ALL TROPICAL PRODUCTS
IMPORTS: ALL TYPES OF MANUFACTURED GOODS
AGENTS: FOR FLOUR- (QUAKER) CANADA
(b) .. HAIRCOSMETICS (WELLA) A.G. GERMANY.
(c) .. VETRINARY & AGRICULTURAL PRODUCTS (GERHADHT PENICK) ENGLAND
(d) .. PAINTS - (CONSOLIDATED PAINTS & VARNISH CORPORATION) OHIO, U.S.A.
(e) .. ALL CLASSES INSURANCE (S. B. I.) AUSTRALIA.

Efficiency, quick service and prompt payment of compensation we offer best advantage to our customers
TRANSPORT: WE HANDLE YOUR GOODS WITH CARE
MAKE QUICK DELIVERY, WE SUPPLY ABUNDANTLY AND WITH COMPARATIVELY LOW PRICES HIGH PRODUCTS. EVERY ORDER RECEIVES OUR CAREFUL ATTENTION.



WOULD YOUR RECORDS be safe?





Model 2016CL

They will be . . . in a genuine MOSLER "C" Label Record Safe!

Withstands severe fire up to 1,700°F. Features famous Mosler "Counter Spy" Dial and bears Underwriters' T-20 Tamper Resistant label. Handsome, modern design by Raymond Loewy . . . available in variety of finishes to match your office decor. Phone us or stop in today!

$000.00

Phone or stop in today!

LEVENTIS TECHNICAL
P. O. Box 159 Phone : 23872
LAGOS


# Ipe ebe fun iranlowo awon odi



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon Oga'gun meji ti nwon mu iwe ebe owo fun iranlowo awon odi ati aditi yika gbogbo awon ilu ti o mba Gesi sepo. Iwe na ni awon Oga'gun meji ti a nwo aworan won yi mu lo si odo Alaiye uwa Oba obinrin ni Afin Buckingham.

**Nwon ti gba oruko gbogbo awon Alakoso, Olotu ijoba, awon Bale ilu ati awon asia pataki-pataki yika gbogbo ilu ti o mba Gesi sepo sinu iwe na.**

## OLOLA NLA DUKE TI DEVONSHIRE
(O bere loju ewe kini

Ninu ayipada ti nwon se fun awon Alase Ijoba Gesi ninu osu October, odun 1960, ni nwon gbe ipo Alase Ijoba ti akowe awon ilu ti o mba Gesi sepo fun Olola nla Duke, o si ti wa ninu Igbimo nla (House of Lords) lati inu odun 1950, nigbati o g'ori oye nla ti baba re gegebi Duke Kokanla.

Oloye nla Duke ti mo origirisi awon ilu ti o mba Gesi se po; o rin yi ile Africa wo pelu iyawo re lehin ogun ekeji, nilu Australia ni irohin iku baba ti dapada silu Oyinbo.

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Phone No 23370